Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 127-139 | jan./ jun.2025.

Ìṣàfihàn onírúurú ọ̀nà ìjóbìnrin nínú àṣàyàn iṣẹ́ ọnà aláwọ̀mọ́ lítíréṣọ̀ yorùbá

Representations of women dynamism in selected yorùbá literary genres

Àrìnpé Gbekelolu ADÉJÙMỌ̀, Ph.D *
ORCID iD https://orcid.org/0009-0006-4603-1402

ÀṢAMỌ̀

Ìmọ̀ nípa ìbáṣepọ̀ tó wa láàrin takọ-tabo ti gbọ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ láàrin àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ lẹ́lẹ́kajẹ̀ka. Obìnrin àti ipò wọn gẹ́gẹ́ bí àṣà àti ìṣe ti fi lọ́lẹ̀ sì jẹ wọ́n lógún. Àwọn onímọ̀ kan gbà pé àṣà àwùjọ Yorùbá n gbé èrò akọ-lo-lórí lẹ́yìn àmọ́ ọ̀pọ̀ ìwádìí lo tún ti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ipò àti ipa pàtàkì ni obìnrin ti kó, tí wọ́n sì tún ń kó láwùjọ Yorùbá. Àfojúsùn iṣẹ́ yìí ni ṣíṣe àyẹ̀wò ipò àti ipa tí obìnrin ń kó nínú ètò àti ẹ̀tọ́ ìlú bí ó ti hàn nínú àṣàyàn lítíréṣọ̀ Yorùbá. Tíọ́rì Ìṣẹ̀tófábo ti Clenora Hudson-Weems ni a gùnlé láti ṣàtúpalẹ̀ àṣàyàn oríkì orílẹ̀, eré-onítàn àti fíìmù Yorùbá tí a mọ̀-ọ́n-mọ̀ yàn láàyò nítorí àkóónú wọn. Àwọn iṣẹ́ ọnà aláwọ̀mọ́ lítíréṣọ̀ náà ni: Akínwùmí Ìṣọ̀lá, *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*, *Olú-Ọmọ, Ẹfúnróyè Tinúubú;* Oríkì Arẹ̀sà bí ó ti hàn nínú Adébóyè Babalọlá *Àwọn Oríkì orílẹ̀ Mẹ́tàdínlógún;* àti fíìmù àgbéléwò *Fúnmiláyọ̀ Ransome Kútì* tí Túndé Babalọlá kọ. Iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ipa pàtàkì ni àwọn obìnrin ti ń kó láwùjọ Yorùbá láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìtàn ṣe fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀. Bákan náà ó hàn pe ajàfẹ́tọ̀ọ́ ọmọnìyàn ní àwọn obìnrin kan. Síwájú sí, ipa tí obìnrin ń kó nínú ètò àti ẹ̀tọ́ ìlú ní ayé àtijọ́ títí di òní kò ṣe é fọbẹ̀ bù dànù. Bákan náà ni iṣẹ́ yìí fi hàn wí pé láti ayébáyé ni àyè ti gba obìnrin ní àwùjọ Yorùbá. Iṣẹ́ yìí tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé lítíréṣọ̀ Yorùbá jẹ́ ohun èlò láti fi ìjóbìnrin lọ́lẹ̀ láwùjọ. Ó sì tún fi hàn pé a le lò ó láti fi èrò báyéserí ẹni múlẹ̀.

AWỌN KOKO

Literature, Women, Gender, Africa, Yoruba

ABSTRACT

Studies on gender discourse in African society has been privileged by scholars in almost all discipline. Existing studies in Yorùbá have focused largely on the cultural tradition and role of women. Generally, the Yorùbá people are assumed to be culturally patrilineal with women often subjugated and marginalized. This study, therefore, using Clenora Hudson-Weems African Womanism approach, this paper was designed to examine the dynamism of Yorùbá women as represented in selected Yorùbá literary genres, with a view to establishing the place of women in human, social and national development. The interpretive design was used to examine one Oríkì orílẹ̀, three plays and a home video purposively selected due to their thematic relevance. They are Akínwùmí Ìṣọ̀lá's *Ẹfúnsetán Aníwúra, Olú Ọmọ* and *Ẹfúnróyè Tinúubú; Oríkì Arẹ̀sà* as documented in Adébóyè Babalọlá's *Àwọn Oríkì Mẹ́tàdínlógún* and Túndé Babalọlá's *Fúnmiláyọ̀ Ransome Kútì.* The texts were subjected to literary analysis. The study reveals that women occupy a significant space in both the pre-literate and contemporary era, with some women emerging as human rights activists and advocates. The paper establishes that Yorùbá literary genres have been used as weapons to negotiate spaces for women, and also as a

* Department of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn, Nigeria, Email: agadejumo@yahoo.com

tool used to herald the voice of women both in the pre-colonial and contemporary Yorùbá society and by extension, the larger Nigerian society.

KEYWORDS
Literature, Women, Gender, Africa, Yoruba

Ìfáàrà

Ìtàn ìṣèdálẹ̀ Yorùbá ti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé takọtabo ni Olódùmarè dá ilé ayé. Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni Olódùmarè ti dá Ìdamùrí àti Èyílà. Ìdamùrí ni ọkùnrin tí Èyílà sì jẹ́ obìnrin. Olódùmarè tó jẹ́ Adẹ́dàá ohun gbogbo kì í sì í ṣe ohun kan laìní ìdí, èrèdìí èyí ni àwọn ènìyàn àwùjọ Yorùbá ṣe pín ojúṣe ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn fún wọn. Nínú ètò ìdílé Yorùbá ẹyẹ kì í fi apá kan fò. Bí ọmọ ba to ni ọkọ́ àwọn Yorùbá a fún un lọ́kọ́. Èyí ló fá à tó fi jẹ́ pé ọmọkùnrin tó bá ti bàlágà tó tó aya fẹ́, àwọn Yorùbá a fẹ́yàwó fún un. Ẹsẹ Ifá kan tilẹ̀ lọ báyìí pé:

Bí a bá láya tán
Ẹni gbangba là á jẹ́

Èyí túmọ̀ sí pé ìgbà tí ọkùnrin bá tó lóbìnrin nílé ní yóò tó di ẹni iyì láwùjọ. Bí a bá wá wo obìnrin gẹ́gẹ́ bí aya tàbí ọmọlọ́ọ̀dẹ̀, onírúurú ọ̀nà ni wọn ń gbà kó ipa láwùjọ àwọn Yorùbá. Gbogbo wa la mọ̀ pé obìnrin a máa kó ipa olùrànlọ́wọ́ àti agbọmọlà. Wọn a máa nípa nínú ìṣèlú, wọn a sì máa ko ipa pàtàkì nínú ètò ọrọ̀ ajé àwùjọ wọn (Adejumo 2017 àti 2022, Adeleke 2017, Bolarinwa 2019).

Nígbà tí a bá ń sọ̀tàn àwọn obìnrin bíi *Mọ́remí,* a ti mọ̀ pé agbọmọlà ni, ó fi ẹ̀mí rẹ̀ wéwu kí àwọn ènìyàn rẹ le rí ìtúsílẹ̀. Bákan náà ni ó sì hàn gbangba pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwùjọ Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní ni wọ́n ní òye ìyálóde, èyí tí wọn le máa pè ní oríṣiríṣi orúkọ ní àwọn àwùjọ kan, bí àpẹẹrẹ:

Lọbun ló dúró bí ìyálóde ni Òndo
Ìyálóde ló dúró bí ìyálóde ni Ọ̀yọ́
Aríṣe ló dúró bí ìyálóde ni Iléṣà

Yàtọ̀ sí kíkó ipa nínú ìṣèlú yìí, a tún rí i pé àwọn obìnrin Yorùbá a máa kópa nínú ogun jíjà. Bí àpẹẹrẹ, àwọn obìnrin Ìdọ̀ọ̀mi àtijọ́ kópa nínú ogun tó wáyé láàrin Ìdọ̀ọ̀mi àti Ègbá nípa jíjà lójú ogun.

Àwọn obìnrin tí kò sì ja ogun lọ́nà tààrà kó ipa ribiribi láti rí i pé ogun kò kó ìlú wọn lọ. Àkíyèsí pàtàkì tí a ṣe ni pé ètò ọrọ̀ ajé àti bí àwọn obìnrin ṣe fìdí múlẹ̀ tó nípa ohun tó rọ̀ mọ́ ọrọ̀ ajé kó ipa ribiribi lórí ipa tí ọ̀pọ̀ wọn kó nínú ìṣèlú tí a mẹ́nu bà lókè yìí. A tún ríi pé jíjà fún ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn jẹ́ ohun tí ó múmú láyà àwọn obìnrin ní ayé àtijọ́ àti lóde òní. Èyí ni ó mú wà walẹ̀jìn lórí obìnrin àti ipa wọn lórí ètò àti ẹ̀tọ́ ìlú láwùjọ Yorùbá bí ó ṣe hàn nínú lítíréṣọ̀ alohùn àti iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ wọn.

Ọgbọ́n Ìṣèwádìí

Àfojúsùn iṣẹ́ yìí ni wíwo ipò obìnrin nínú ètò àti ẹ̀tọ́ ìlú. Àwọn lítíréṣọ̀ Yorùbá kan tí ó mẹ́nu ba ìwà àti ìṣe obìnrin tí ó jẹ mọ ìdàgbàsókè àwùjọ lápapọ̀ ni a mọ̀ ọ́n-mọ̀ ṣà yàn fún ìtúpalẹ̀. Détà fún àyẹ̀wò ní oríkì orílẹ̀ Arẹ̀sà; ìwé eré-onítàn mẹ́ta; *Ẹfúnṣetán Aníwúra*, *Olú Ọmọ* àti *Ẹfúnróyè Tinúubú;* àti fíìmù àgbéléwò *Fúnmiláyọ̀ Ransome Kutì*. Ẹ̀dá ìtàn obìnrin ni olú ẹ̀dá ìtàn àwọn eré-onítàn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta àti fíìmù tí a yẹ̀ wò. Àṣàyàn oríkì orílẹ̀ tí a mẹ́nu bà sì kún fún akínkanjú obìnrin. Tíọ́rì ìṣẹ̀tọ́fájo ni a fi ṣe àtẹ̀gùn fún ìtúpalẹ̀ wa.

Tíọrì ìṣètọ́fábo jẹ́ ẹ̀yà tíọ́rì ìṣègbèfábo, àmọ́ ojú ìwòye rẹ yàtọ̀ gédégbé sí tíọ́rì ìṣègbèfábo. Àfojúsùn tíọ́rì ìṣètọ́fábo ni ìṣàpọ́nlé bí àwọn obìnrin aláwọ̀ dúdú ṣe ń ṣe akáko

ìpèníjà tó ń dojúkọ wọ́n nínú ìgbé ayé wọn (Kọ́láwọlé 1997). Bákan náà, ọ̀rọ̀ ẹbí àti gbogbo ìgbáyégbádùn ènìyàn jẹ́ tíọ̀rì ìsètọ́fàbo lógún. Fífi ẹ̀tọ́ ẹni fún ni, ìbá ṣe ọkùnrin tàbí obìnrin ni ààringnbungbun ohun tí ó gbé tíọ̀rì yìí ró (Nwajiakwu 2004).

Tíọ̀rì yìí mọ rírì agbára àti akitiyan awọn obìnrin Áfíríkà kí ìjọba amúnisìn tó wọ àwùjọ, ó sì tako fífi ọkùnrin ṣe àfojúsùn ohun gbogbo. Bákan náà ni tíọ̀rì yìí lòdì sí fífi ojú àmúwáyé àwọn Gẹ̀ẹ́sì wo gbogbo nǹkan (Ọmọtayọ, 2025). Parípari rẹ̀, ọ̀nà tí a gbà tú iṣẹ́ yìí palẹ̀ ní lílo ìfojú-lítíréṣọ̀-wò àti ìlànà ìfojú-àṣà-wò lítíréṣọ̀ láti ṣàlàyé èrò wa nínú iṣẹ́ yìí ìtúpalẹ̀ tọ́nà-ìfójú-lítíréṣọ̀ àti àṣà wo ni a fi ṣàlàyé gbogbo èrò wa nínú iṣẹ́ yìí.

Obìnrin Yorùbá àti ipa wọn lórí ìdàgbàsókè ajẹmọ́-ọrọ̀ ajé

Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni àwọn Yorùbá ti ṣe àlàkalẹ̀ ojúṣe àwọn obìnrin; ọ̀rọ̀ iṣẹ́ ti obìnrin yóò ṣe sì jẹ́ mọ òwò ṣíṣe ní gbogbo ọ̀nà. Ohun àkọ́kọ́ tí a gbọ́dọ̀ mọ̀ ni pé iṣẹ́ àgbẹ̀ ni iṣẹ́ àwọn bàbá ńlá Yorùbá. Àwọn ọkùnrin ilé ni yóò roko, kọbè tí wọn yóò si gbin ohun ọ̀gbìn. Nígbà tí àwọn ọkùnrin bá parí iṣẹ́ tiwọn, ojúṣe àwọn obìnrin ni láti rí i pé erè oko tí àwọn ọkùnrin kórè á di títà. Gẹ́gẹ́ bí èrò Fádípẹ̀ (1970), àwọn aya ni yóò ta erè oko. Ọ̀nà tí wọn le gba ṣe èyí pọ̀, wọn le ta èrè oko yìí bí ó ṣe jáde gan-an, nígbà mìíràn wọn sì le ṣe àtúnrọ̀ rẹ̀ sí oríṣiríṣi nǹkan. Ìdí nìyí tí ó fi gbà pé ojúṣe obìnrin ni pé kí wọn rí i dájú pé erè oko di jíjẹ. Nígbà mìíràn àwọn obìnrin ni yóò ṣe àmójútó àwọn erè oko tí kòkòrò kò fi ní jẹ wọn tàbí kí wọn bà á jẹ́. Bí a bá tilẹ̀ wo oríkì àwọn Arẹ̀sà, a óò rí èrò òkè yìí:

Tí ń bá ń lọ ìfarahàn ilé ìrẹ̀sà Báníọlá, ọmọ dúdú
Ohun mẹ́ìndínlógún ni ò jọ́mọ
Onírẹ̀sà máa gbélé oko
O o r íí? N ó pa gbẹ́rẹ́ n ó lo
Rè é ké sákọ̀pẹ
Ki jẹ́ kí ọmọ Oníresà máa gbé lé ọkọ
Akọ̀pẹ kọ̀pẹ tán
N ó lọ rè é kẹ́yìn mi
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Ma ru ẹyìn sẹ́kù
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Ọ̀túnla máa sae`rè ẹyín
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Ma ségi wale
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Ma pọnmi ẹ́kù
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Ma dáná mọ́ ẹyìn lónìí
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Má tún wọ́ ẹyìn lọ́la
Ọ̀ní n o lọ rèé t’nẹ́ku ṣe ń lè wa
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Ma mépo bọ̀ lẹ́kù
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Ma gbá jù epo
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Ma dín kẹ̀tẹ́
Èètán ni ń ó fòní dín ń lé Baríọlá
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ
Má jan ihá
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹsà máa gbé lé ọkọ

Ma rèkùrọ́ wale
Ma repo wálé
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹṣà máa gbé lé ọkọ
Arepo ra epo
Ma repo wale
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹṣà máa gbé lé ọkọ
Arepo ra epo
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹṣà máa gbé lé ọkọ
Ẹni ó repo kò san wó epo
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹṣà máa gbé lé ọkọ
Dandan gbọ̀n-ọ́n gàndán lónìí ni ń ó gbowó
Epo òhún lódọ̀ ẹni ó repo
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹṣà máa gbé lé ọkọ
Àkújìjàdú oyè Mọdẹ Ìrẹsà
(Babalọlá 2000: 106-107)

Bí a bá ṣàkíyèsí oríkì òkè yìí fínnífínní, a óò rí i pé yàtọ̀ sí pe àwọn obìnrin Arẹsà gbé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbésẹ̀ láti rí i pé ẹyìn kúrò ni ipò èso ẹ̀yìn lásàn nípa ọ̀pọ̀lọpọ̀ akitiyan tí wọ́n ṣe láti mú un jáde bí èkùrọ́, ahá, ìkẹ̀tẹ́, èèsàn àti epo tí ó jẹ́ olúborí àwọn ohun tí ó ń ti ara èkùrọ́ jáde. Èyí fi hàn pé àwọn ọmọbìnrin Arẹ̀sà jẹ́ òpó pàtàkì nínú ìṣẹ̀dá ohun èlò àti ohun jíjẹ tí ó lè mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ. Bákan náà ni ìgbésẹ̀ ìkẹyìn fi hàn gbangba pé òwò ṣíṣe jẹ́ àwọn obìnrin Ìrẹ̀sà lógún.

Arepo ra epo
Ẹni o repo ko sanwó
Dandan gbọ̀n-ọ́n gàndán lónìí ni ń ó gbowó
epo ọ̀hún lọ́dọ̀ ẹni ó repo

Oríkì àwọn obìnrin Àrẹ̀sà òkè yìí ló ń ṣàfihàn ojú tí àwọn obìnrin fi mú ọ̀rọ̀ òwò ṣíṣe láwùjọ Yorùbá. Ọwọ́ yẹpẹrẹ kọ́ ni àwọn obìnrin fi mú síso tọ́rọ́ di sísì. Àwọn ọkùnrin náà mọ èyí, ìdí nìyí tí Ọ̀rúnmìlà nínú Odù Ifá Èjìogbè fi ran aya rẹ, láti lọ sòwò nínú ẹsẹ Ifá ìsàlẹ̀ yìí:

Ọ̀dá owó awo kóro
Ààbò obìnrin rẹ ọmọ wọn lóde
Ìjerò
Bí ọdá owó ti ń dá mi
Bẹ́ẹ̀ ni ààbò mi ń bò mi
A díá fún Ọ̀rúnmìlà
Lọ́jọ́ tí olojò méta
Ó wọ̀ sílé bàbá
Ifá ò sì nii ookán à á yọ́ọ̀ ná
Ní Ọ̀rúnmìlà bá pe ààbò, obìnrin rẹ̀
Pé kí ó kọ́ àwọn nǹkan ìní òun
Lo sọ́jà lọ ọ tà
Ni ààbò bá mówó ra oúnjẹ wálé
Àwọn olojò mẹ́tẹ̀ẹta náà ikú àrùn àti
Èṣù jẹ
Nwọn sì yó...
(Abímbọ̀lá 1968: 20-21)

Ohun tí a ń fìdí rẹ̀ múlẹ̀ ni pé àwọn obìnrin Yorùbá ti ń sòwò láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ wá. Èrò Ọ̀pẹ́fèyítimi (2009:13) sì ni pé púpọ̀ nínú òwò tí àwọn obìnrin ń ṣe ló rọ̀ mọ́ ojúṣe wọn gẹ́gẹ́ bí aya àti ọmọ nínú ilé. Ará ojúṣe ọmọbìnrin nínú ilé ni oúnjẹ ṣíṣe. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára iṣẹ́ tí wọn yàn láàyò. Àwọn obìnrin Yorùbá a máa ṣe oúnjẹ tà. Bí ọ̀làjú ṣe ń de sí àwùjọ ni òwò ṣíṣe tó rọ̀ mọ́ oúnjẹ ń gbilẹ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìyá àpọ́n ló wà káàkiri àwọn ìlú ńlá báyìí. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ilé iṣẹ́ ńlá tàbí agbègbè tí onírúurú ilé iṣẹ́ bá wa ni wọn máa ń pabùdó sí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òwò àwọn Ìyá àpọ̀n ni wọn ń ṣe, ipa ti wọ́n ń kó lórí bí iṣẹ́ àwọn tó ń ṣiṣẹ́ ní ilé iṣẹ́ ńlá yóò ṣe rewájú, tí yóò sì gbọ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ kò kéré. Nípa bẹ́ẹ̀ wọn ń mú ìdàgbásókè bá ètò ọrọ̀ ajé orílẹ̀-èdè wọn lápapọ̀.

Kì í ṣe oúnjẹ pípèsè nìkan ni àǹfààní tí a lè rí nínú bí àwọn obìnrin ti ń ṣe oúnjẹ ta yìí o. Wọ́n tún ń ṣe ojúṣe ajẹmọ́ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ láwùjo. Kì í ṣe òwò tó jẹ mọ́ oúnjẹ ṣíṣe tà nìkan ni àwọn Yorùbá máa ń ṣe, ìwádìí fi hàn pé ìrísí àti àbùdá àwọn obìnrin tún tọpa àwọn iṣẹ́ tí wọn yàn láàyò. Èyí ni Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2009) fi sọ pé iṣẹ́ oúnjẹ títà ti di okòwò tí ó pọn dandan fún àwùjọ láti kááràmásìkí. Lójú Ọ̀pẹ́fèyitimi (2009:40) àwọn àbùdá kan wa tí a mọ̀ mọ́ obìnrin ni ṣíṣe oge àti bíbú ẹwà kún ẹni.

> “the virtues of beauty patience and rhetoricity as virtues of occupational values which are also associated with women”
>
> Àwọn àbùdá ẹwà ajẹmọ́-sùúrù àti ìmẹ̀sọ ọ̀rọ̀ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ohun tó dára níí ṣe pẹ̀lú iṣẹ́ tí àwọn obìnrin kà sí tí a sì mọ̀ mọ́ wọ́n.

Ìdí nìyí tó jẹ́ pé àwọn òwò tó jẹ mọ́ bíbu kún ẹ̀wà àti oge ṣíṣe fún ara ẹni/àti obìnrin ẹlẹgbẹ́ ẹni jẹ́ àwọn obìnrin lógún. Bí àpẹẹrẹ ọ̀kan lára iṣẹ́ tí obìnrin yan láàyò ni irun dídì. Àti ẹni tí a ń dirí fún àti ẹni tó ń dirí ni ó sì nílò sùúrù púpọ̀. Àbùdá ohun to rẹwà ti Elédùwà fi jíǹkí àwọn obìnrin lo sì tún fún wọn ni àǹfààní àti máa kiri onírúurú ọjà, kò sí ohun náà tí àwọn obìnrin ko le kiri ni àtijọ́. Wọn a máa kiri mọ́ínmọ́ín, àkàrà, irú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lóde òní ẹ̀wẹ̀, onírúurú ọ̀nà ni obìnrin ń gbà polówó ọjà. Èyí tó gbòde ni ìpolówó ọjà lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ nípa lílo ìlànà tọ́rọ-fọ́n-kálé bí i wàsáàpù, ínsítágíráámù, fesibúùkù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ó yẹ kí á fi kún un pé lóde òní, tọkùnrin tobìrin ló ń ṣe àwọn òwò yìí.

Àmọ́ àwọn òwò kan tilẹ̀ wà tí Ọ̀pẹ̀feyitimi (2009) pé ni òwò àwọn ìyá, irú òwò bẹ́ẹ̀ ni asọhíhun, lékuléja àti epo títà. Lójú tirẹ̀ àwọn obìnrin ni wọ́n máa ń ṣe àwọn iṣẹ́ yìí (Ọpẹfeyitimi 2009:)

Ọ̀sanyìn tó jẹ́ ọmọ ẹ̀kọ́ṣẹ́ Ọ̀rúnmìlà ló kọ́ ọ bí a ṣe é lo ewé fún ìwòsàn àwọn ẹ̀dá ọwọ́ Elédùà. Ọ̀rúnmìlà ló wá fi iṣẹ́ alágbo ọmọ yìí lé àwọn ìyàwó rẹ̀ lọ́wọ́. Títí di òní ni àgbo ṣíṣe yìí sì jẹ́ òwò pàtàkì tí àwọn obìnrin Yorùbá máa ń ṣe. A tilẹ̀ rí i pé àwọn obìnrin kan ti ń ṣe sínú ìgò kékèkè tí yóò fi bá ìlànà ìpòó ìlànà ìpòògùn tí gbogbo àgbáyé mu.

Ohun tí á rí fàyọ nínú obìnrin àti òwò ṣíṣe ni àwùjọ Yorùbá ti fi hàn pé obìnrin Yorùbá kò fi ìgbà kankan ya ọ̀lẹ. Kò sí obìnrin Yorùbá tíí káwọ́ gbera tí kò ni ṣe nǹkan kan. Láti kékeré ti ìmọ̀le ti ń kọ ọmọ rẹ̀ lẹ́sìn ni àwọn obìnrin Yorùbá tí i fi iṣẹ́ ṣíṣe àti òwò ṣíṣe kọ àwọn ọmọbìnrin wọn. Ní kékeré ni ọmọbìnrin tí i bá ìyá rẹ kiri ọjà káàkiri, nípa èyí yóò ti mọ bí a ṣe ń sọ pọ́ùn kan di pọ́ùn méjì. Ìgbà mìíràn tilẹ̀ wà tó jẹ́ pé òwò tí ìdílé wọ́n ń ṣe ni àwọn ọmọbìnrin máa ṣe nílé ọkọ tiwọn, a sì rí àwọn obìnrin mìíràn tí yóò tún mú òwò tí wọ́n ń ṣe ní ìdílé ọkọ wọn mọ́ èyí tí wọn ti mọ̀ nílé bàbá wọn.

Bí a bá tilẹ̀ wo àṣà ìdána ni àwùjọ Yorùbá, a óò rí i pé abala kan lára rẹ̀ fi hàn pé àwọn obìnrin Yorùbá kì í sọ̀lẹ. Nínú ètò ìdána ọkọ ìyàwó àti àwọn ènìyàn rẹ̀ yóò ta ìyàwó lọ́rẹ̀. Ọkọ ìyàwó ni yóò kó ẹ̀bùn owó tí ìyàwó bá gbà sínú àpamọ́wọ́ ìyàwó rẹ̀ lẹ́yìn èyí ni yóò wúre sí i. Lára ìwúre tí wọn yóò wú sí i ni pé öwó tí ọkọ ìyàwó fún aya rẹ̀ yóò fi sòwò yóò fi jèrè, yóò si di ìlọ́po ìlọ́po.” Èyí túmọ̀ sí pé ìrètí ọkọláya àti àwùjọ ni pé kí ìyàwó sòwò kó jèrè.

Obìnrin Yorùbá àti òwò Ṣíṣe nínú Ìtàn

Àwọn onímọ̀ ìtàn ti ṣiṣẹ́ takuntakun láti fi hàn pé ipa tí obìnrin kó nínú òwò ṣíṣe láwùjọ Yorùbá kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn rárá. Denser (1994:252) tilẹ̀ fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ṣáájú dídé àwọn òyìnbó sí àwùjọ Yorùbá òpó pàtàkì ni àwọn obìnrin jẹ́ nínú ètò ọrọ̀ ajé àwùjọ wọn. Ó tilẹ̀ fi ìrírí Clapperton ni ọdún 1862 nípa àwọn ìyàwó Aláàfin Ọ̀yọ́ kin èrò rẹ̀ lẹ́yìn nígbà tó ní:

> "The kings of Eeyeo's (Oyo's) wives are to be found trading for him, and, like other women of the common class, carrying large loads on their heads from town to town" (Denzer 1994:6)
>
> "Àwọn ayaba Aláàfin Ọ̀yọ́ ni wọ́n ń gbowó pẹ̀lú àwọn obìnrin mìíràn tí wọn ń ru ẹrù láàrin ìlú fún títà"

Àkọsílẹ̀ àwọn onímọ̀ ìtàn sì tún fi yé ni pé àwọn obìnrin lo máa ń ṣagbátẹrù ọjà, àwọn ni wọn sì jẹ́ olóyè tó ń mójú tó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjà. Èrò yìí ló fi hàn nígbà tó ni:

> "The Lander brothers reported that in Egga, a loading trade centre, women were "the chief, if not the only traders" and most adept at all "those petty tricks and artifices in their dealings with which the civilized countries are acquainted" (Denzer 1994:6)
>
> Àwọn arákùnrin Lander tilẹ̀ kọ ọ́ sílẹ̀ pé ní Egga, ibùdó òwò ṣíṣe, àwọn obìnrin ni olóyè tí wọ́n sì ń tajà níbẹ̀, gbogbo wọn ní ìmọ̀ọ́ṣe tó tayọ gbogbo ọgbọ́n àti àyínìke òwò ṣíṣe bí ó ti wà ní àwọn orílẹ̀-èdè tó lajú ni àwọn náà sì mọ̀.

Ní sẹ́ńtúrì mọkàndínlógún sẹ́yìn ìtàn fi hàn pé àwọn obìnrin ló kan tiẹ̀ gba òwò ṣíṣe pẹ̀lú àwọn òyìnbó aláwọ̀funfun kanrí. Gẹ́gẹ́ bí àkọsílẹ̀ Hinderer, arákọ̀nrin Lander àti Clapperton nípa Badagry àti Ìbàdàn, àwọn iṣẹ́ tí obìnrin gbà kanrí ni aró rirẹ (àdìrẹ), aṣọ híhun, epo ṣíṣe àti adin ṣíṣe pẹ̀lú iṣẹ́ ọṣẹ (6).

Ìrírí àwọn onímọ̀ ìtàn tiẹ̀ fi hàn pé kò sí ibi tí àwọn obìnrin Yorùbá kì í fi ẹsẹ̀ rìn dé láyé àtijọ́ láti lọ ṣe òwò. Ìdí nìyí tí Johnson fi ṣe àfiwé àwọn obìnrin Yorùbá (Ìbàdàn) pẹ̀lú àwọn ọkùnrin wọn nígbà tó ni:

> "The women of those days were as hardy as the men, and often went in a body as caravans- to Ìkirè and Apòmù for corn and other foodstuffs although the road was unsafe from kidnappers. They supplied the town with food whilst the men were engaged in slave hunting" (Johnson: History of the Yoruba: 245)
>
> Àwọn obìnrin ayé ìgbà náà lágbára bí ọkùnrin, ọ̀pọ̀ ìgbà ní wọ́n ń rin ìrìnàjò aĺárìnpapọ̀- láti Ìkirè lọ sí Apòmù láti lọ ra àgbàdo àti àwọn oúnjẹ mìíràn, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ewu wà lójú ọ̀nà nítorí àwọn ajínigbé. Wọ́n ń ta oúnjẹ sí ìlú náà nígbà tí àwọn ọkùnrin ń ṣe iṣẹ́ ọdẹ

Ohun kan tí ó ṣe pàtàkì nínú òwò tí àwọn obìnrin yìí ń ṣe ni pé àwọn obìnrin Yorùbá kò fi ìgbà kan dírèbẹ̀ẹ̀ lọ́dọ̀ akọ. Bí àwọn ọkùnrin ṣe ń mójú to ọ̀rọ̀ wọn bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn obìnrin yìí ń mójú tó ọ̀rọ̀ tiwọn náà láàyè ara wọn. Èyí ni Denzer (1994:7) sọ nígbà tó ni:

> Yorùbá women controlled their own economic activities and the profits made form them. Big traders employed both slaves and freeborn both slaves and freeborn labour (male and female), fixed prices, controlled the movement of goods, and established and ran their own crafts guilds or association (Denzer 1994:7)

> Àwọn obìnrin Yorùbá lo ń sàkóso òwò wọn àti èrè tí wọn bá ríníbẹ̀. Àwọn onísòwò aládàá ńlá máa ń ní tẹrútọmọ to ń ṣiṣẹ́ fún wọn (lọ́kùnrin lóbìnrin), wọn a má díye lọ́jà, wọn a sì máa sàkóso bí a ṣe ń ta àwọn ọjà kan, ní ọ̀pọ̀ ìgbà ní wọn sì máa ń dá ẹgbẹ́ irú ọjà tí wọ́n ń tà sílẹ̀.

Àkíyèsí òkè yìí ló ń fi hàn pé kì í ṣe ipa kékeré ni àwọn obìnrin ń kó. Àpẹẹrẹ àwọn obìnrin Yorùbá tó lẹ́nu nínú ìṣèlú fi hàn pé púpọ̀ nínú àwọn obìnrin Yorùbá tó jẹ oyè ìyálóde ni àwùjọ Yorùbá sáájú dídé àwọn òyìnbó sí àwùjọ àti lásìkò tí àwọn òyìnbó amúnisìn ń ṣe ìjọba títí di òní olónìí ti fi hàn pé obìnrin kò kẹ̀rẹ̀ nínú òwò ṣíṣe bẹ́ẹ̀ sì ní ipa tí wọ́n ń kó kò kéré rárá.

Àfihàn Onírúurú Ọ̀rọ̀ Ìjóbìnrin nínú Àṣàyàn Iṣẹ́ Ọnà Aláwòmọ́ Lítíréṣọ̀

Báyìí, a óò gbìyànjú àti mẹ́nu ba díẹ̀ lára àwọn akitiyan obìnrin àti ipa tí wọn kó nínú òwò ṣíṣe, ìṣèlú àti ìjàfẹ́tọ̀ọ́ ọmọnìyàn bí ó ti hàn nínú iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀. Lákọ̀ọ́kọ́ àfihàn obìnrin àti ìdàgbàsókè àwùjọ nínú eré onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà, Olú Omọ* àti *Ẹfúnróyè Tinúubú* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ ni a ó yẹ wò.

Tinúubú ni ìyálóde àkọ́kọ́ ní ìlú Abẹ́òkúta. Ìtàn sì fi yéni gbangba pé ipa pàtàkì ni Tinúubú kó nínú òwò ṣíṣe nígbà ayé rẹ̀. A sì rí i pé ó já fítafíta láti kojú ìjọba amúnisìn ni ìlú Èkó nígbà ayé rẹ̀. Òye ipa ti Tinúubú kó nínú òwò ṣíṣe hànde dáadáa nínú eré-onítàn tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ nípa rẹ̀. Nínú *Olú Ọmọ,* lẹ́yìn ti Tinúubú ti fi ìlú Èkó sílẹ̀ wá sí Abẹ́òkúta, àwọn ará Èkó rán Asọ̀gbọ́n àti Adéoyè wá bẹ̀ ẹ pé kí ó padà wá sí Èkó ṣùgbọ́n Tinúubú kọ jálẹ̀. Ó wá sọ nípa ara rẹ̀ pé:

> Èmi o sọ pé n ò níí ràn yín lọ́wọ́ o. Ohun ti mo wí ni pe n ò wáá jókòó sí Èkó mọ́. Ṣùgbọ́n gbogbo ohun tí ẹ bá fẹ́ kí ń ṣe ni ń ó ṣe. <u>Mo lọ́mọ́ ogun, mo lọ́ta, mo lẹ́tù, mo lówó, mo léèyẹn, mo sì lẹ́nu</u> *(Olú Ọmọ: 7).*

Nínú eré-onítàn yìí kan náà, òǹkọ̀wé fi èrò rẹ̀ nípa ipò pàtàkì tí Tinúubú ń kó gẹ́gẹ́ bí onísòwò láwùjọ rẹ̀ hàn. Adébógùn ni òǹkọ̀wé fi èrò yìí sí lẹ́nu nígbà tó ní:

> Nílẹ̀ yìí àti lẸ́kòó, ẹ wà láàyè tí ẹ ti le rí owó, ọta, etù-ìbọn lọ́pọ̀lọpọ̀. A sì mọ̀ pé bí ogun bá dé, àwọn ìlú ń sá bọ̀ wáá bá yín fún ìrànlọ́wọ́ ní gbogbo ọ̀nà. Ẹ máse dá wọn lóhùn. Ẹ jẹ́ kí a jọ má wò wọ́n níran. Bóyá ẹ lè máa ro ti owó tí ẹ le pàdánù <u>tí ẹ kò bá ta ohun ìjà fún Ẹ̀gbá.</u> Gesó àti Posu ti fi owó ránṣẹ́ sí Kòsọ́kọ́... kódà mo mú díẹ̀ lọ́wọ́ wá fún yín (*Olú Ọmọ: 7)*

Nínú àyọlò òkè méjèèjì yìí, ó hàn gbangba pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Tinúubú kò dí oyè kankan mú láàrin ìlú, ipò tó wà ju ti olóyè lọ, kòṣeémánìí ni. Ọ̀rọ̀ rẹ̀ kò ṣe é kó dànù. Ipa

pàtàkì ló sì ń kó nínú ìṣèlú Ẹ̀gbá. Bákan náà nínú *Ẹ́fúnróyè Tinúubú* Ìṣọ̀lá tún ṣe ìtẹnumọ́ ojúwòye rẹ̀ nípa obìnrin gẹ́gẹ́ bí i onísòwò aládàáńlá. Àyọlò ìsàlẹ̀ yìí ni a óò fi ṣe ìtìsẹ̀.

> Adéjùmọ̀: Mo kí Kábíyèsí, mọ ki Ajẹ́lẹ̀ ẹ̀yin ìjòyè àti ẹ̀yin ará mi gbogbo. Gbogbo wàhálà wa lÉkòó pátá kò ṣẹ́ lórí ẹyọ ẹnikanṣoṣo. Ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ yìí Ẹfúnróyè Tinúubú. Ìwà ayéàtijọtijọ́ pátá lóbìnrin yìí sì ń hù. Ayé igi tí Ṣàngó bá pa àpagbé ló sì ró pé a wà. Bí a bá ń sọ̀rọ̀ òwò àti àṣà ìbílẹ̀ ó má jọra rẹ̀ lójú... ó yẹ kí a mọ ìtàn arábìnrin yìí kí a le mọ́ ohun tó ń dùn un. Ohun ti ó jẹ́ kí ó kórìíra àwọn òyìnbó àti àwon Màrò ni pé... nídìí òwò ṣíse kò fẹ́ẹ́ rí ẹnìkejì... (Ẹfúnróyè Tinúubú:69).

Bí a bá wo àwọn wúnrẹ̀n tí a fa ìlà sí yìí, a óò rí i pé àwọn èèbó gan-an gbà pé ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ ni Tinúubú, wọn sì mọ̀ dájú pé ọ̀rọ̀ òwò ṣíṣe rẹ̀ tayọ; ọ̀rọ̀ Tinúubú kọjá ọ̀rọ̀ àjànàkú tí ó kọjá tí a ní a rí nǹkan fìrí.

Ipa pàtàkì tí Tinúubú tilẹ̀ kó nínú òwò ṣíṣe ni sáà tirẹ̀ hàn nínú díde tí àwọn òyìnbó to jẹ́ oníbàárà rẹ̀ dìde ìrànlọ́wọ́ fún un nígbà tí ìjà bẹ̀rẹ̀ láàrin òun àti Dosùnmú tí í ṣe ọba. (o.i 81-86). Nínú ọ̀rọ̀ tó ti ẹnu Tinúubú jáde sí àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ onísòwò òyìnbó yìí gan-an ó hàn gbangba pé onísòwò tó ti di igi àlọ́yè ni Tinúubú.

Tinúubú: Ẹ dákun ẹ má abọ̀. Mo nílò yín o. Èmi ti mo ti ta gbòǹgbò ka gbogbo Èkó ni ẹnìkan wáá fẹ́ẹ́ fọwọ́ kan fàtu bẹ́ẹ̀. Ọwọ́ ọmọdé wo ló le ka igi ọsè? Ìtàkùn tó bá sì ni kérin máṣe jánà, tòun terin ló ń lọ. Bí abìrùsóóró bá ń ṣe lọ́ńku-lọ́ńkú ǹ jẹ́ o ṣe é mú jù sápò? (82).

Ìbásepọ̀ ààrín Tinúubú àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ fi hàn pé a kò le sọ pé tobìnrin báwo tí a bá ń sọ̀rọ̀ òwò ṣíṣe láwùjọ àti ọrọ̀ níní a kò leè kó wọn mẹ́rẹ̀.
Níbi tí àwọn obìnrin tilẹ̀ takan òwò ṣíṣe de ni sáà yìí, àwọn òyìnbó onísòwò a máa fún wọn lówó àfúnsílẹ̀ láti ra ọjà dè wọn. Àrífàyọ yìí jẹ jáde nínú ìmọ̀ràn tí ìyá àgbà fún Tinúubú nígbà tí ó ń bẹ̀ ẹ́ pé kí ó jèbùrẹ́.

Ìyá: Ní sùúrù Tinúubú káwọ́ gbera, o fetí sílẹ̀. Àwọn onísòwò òrẹ́ rẹ̀ àti dúdú àti funfun tí wọ́n ń gbèjà rẹ̀, sebí nítorí owó wọn tó wà lọ́wọ́ rẹ ni. Owó wọn pọ̀ lọ́wọ́ rẹ̀, kò sì dá wọn lójú pé owó ò ní í wọgbó bí ó ba lọ lÉkòó (o.i 101).

Bákan náà tí a bá wo ìgbésí ayé àwọn ìyálóde tí ó ti jẹ ní ìlú Ìbàdàn láti orí ìyálóde àkọ́kọ́ tí í ṣe Ṣubúọ̀lá (1850-1867) tító de orí ìyálóde tó wà lórí oyè lónìí, onísòwò pàtàkì ni gbogbo wọn. Ṣubúọ̀lá (1850-1857) jẹ́ oníṣòwò tí ń ta ohun ìjà ogun. Ẹfúnṣetán Aníwúrà náà máa ń tá ohun ìjà ogun, ó lówó, ó lọ́rọ̀, ìtàn sì fi yé wa pé ó máa ń yá àwọn ìjòyè àti ológun lówó (Denzer 1994:9-11). Ní pàtó , ohun tí Denzer sọ nípa Ẹfúnṣetán Aníwúrà nìyí:

> She was trained as a trader, specializing in adìrẹ and foodstuffs... she brought her trade acumen to her marital home where she sold corn bees (onka), firearms, and foodstuff. Her customers were mainly soldiers and chiefs, to whom she often extended credit. She owned farms near Ikija karcole and at Odo Ona in Ìjẹ̀bú-òde and Abéòkúta roads respectively. Her slaves, claimed to number one thousand, operated these plantations, producing palm-oil and food (Denzer 1994:10-11)
>
> Ó jẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ oníṣòwò, tó ń ta àdìrẹ àti oúnjẹ lóríṣiríṣi... O mú

> Ọgbọ́n okòwò ṣíṣe rẹ̀ weá sí ilé ọkọ rẹ̀ níbi tó ti ń ta àgbàdo, àwọn ohun èlò ogun jíjà, àti ouńjẹ. Àwọn oníbàárà rẹ̀ ni àwọn jagunjagun àti àwọn olóyè, tó sì máa ń ta ọjà àwìn fún wọn. Ó ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ oko káàkiri ní Ìkijà, Ìjẹ̀bú òde àti ní Abẹ́òkúta. Àwọn ẹrú rẹ̀ tí ó tó ẹgbẹ̀rún, ló máa ń bá a dá àwọn oko náà, tí wọn ń ṣe epo pupa àti oúnjẹ.

Èyí túmọ̀ sí pé láti ayébáyé títí di àsìkò yìí ni àwọn obìnrin ti ń kó ipa pàtàkì nínú ṣíṣe àgbéjáde àwọn ohun èlò bí oúnjẹ, ohun mímu, àṣọ, abbl, fún ìgbáyégbádùn àwọn ènìyàn àwùjọ àti ìdàgbàsókè ètò ọrọ̀ ajé àti àwùjọ lápapọ̀.

Àwòrán ohun tí ìtàn sọ nípa Ẹfúnṣetán Aníwúrà ni Ìṣọ̀lá fi ṣe ìtìṣẹ̀ láti kọ eré-onítàn rẹ̀ *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*. Àfiwé eré-onítàn àti fíìmù sì jẹ́ kí a rí díẹ̀ lára ìwà rere tó wà lọ́wọ́ rẹ̀. Ìpòrógán tí ó wáyé nínú fíìmù yìí sì jẹ́ kí a mọ̀ pé ètò ọrọ̀ ajé Ẹfúnṣetán Aníwúrà tó rú gẹ́gẹ́ wà lára ìdí tí Látóòsà fi ń bá a jà, tí òun àti àwọn olóyè rẹ̀ sì rẹ́yin rẹ̀. Àmọ́ ṣaájú ìpórógàn yìí, a rí àìmọyé ìgbà tí Ẹfúnṣetán ń fi ọwọ́ ọlá rẹ̀ kó tẹrú tọmọ mọ́ra.

Aníwúra gẹ́gẹ́ bí obìnrin tí a fojú rí kòrò àti ẹ̀dá ìtàn inú ìwé tilẹ̀ se àfihàn bí àwọn obìnrin àwùjọ Yorùbá ṣe mú ọ̀rọ̀ òwò ṣíṣe. Lọ́nà kìíní, Ẹfúnṣetán fẹ́ kí gbogbo obìnrin mọ òwò ṣe:

> Ẹfúnṣetán had a conventional upbringing... it is not unlikely that like most Ẹgba girls, she learnt to make adìrẹ cloth (the tie and die) but Ẹfúnṣetán found her vocation in the world of trade... when she was in Abẹ́òkúta, her trading activities had only four or five focal points – Ìbàdàn and Abẹ́òkúta... Port Novo, Badagry and Lagos... (Awẹ́ 1992: 70-71).
>
> (Ẹfúnṣetán náà dàgbà bí a tií dàgbà láwùjọ... kò sí àníàní pé gẹ́gẹ́ bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọge Ẹ̀gbá, ó kọ́ iṣẹ́ àdìrẹ ṣíṣe, ṣùgbọ́n Ẹfúnṣetán rí iṣẹ́ okòwò ṣíṣé gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà tirẹ̀... nígbà tó wà ní Abẹ́òkúta, ọ̀nà mẹ́rìn tàbí márùn-ún péré ni ọwọ́jà okòwò ṣíṣe rẹ̀ dé - Ìbàdàn àti Abẹ́òkúta... Port Novo, Badagry àti Èkó)

Gẹ́gẹ́ bí akin ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ Tinúubú, Ẹfúnṣetán náà bá àwọn òyìnbó da òwò pọ̀ lọ́pọ̀lọpọ̀. Lára wọn ni 'Jamaní, Faransé, Ọsirélíà àti àwọn Gẹ̀ẹ́sì (Awẹ́ 1992: 79). Kò sì sí ohun tí àwọn òyìnbó ń ta ti Ẹfúnṣetán kò ba wọn tà. Ó ta àwọn ọjà bí i tòbákò, sègí, aṣọ, ọtí líle – sìnáàpù (Awẹ́ 1992:79). Níbi tí ó lọ́rọ̀ dé àwọn ẹrù rẹ̀ a máa hun kíjìpá ti wọn ń tà sí apá gúúsù Amẹ́ríkà.

Ọrọ̀ tí Ẹfúnṣetán àti Ẹfúnróyè Tinúubú ni ló sọ wọn di ìlú-mọ̀-ọ́n-ká, tí wọn sì di abẹnugan nínú ìṣèlú. Bí a ba wo akitiyan àwọn àpẹẹrẹ onísòwò obìnrin méjèèjì yìí, àrífàyọ tí a ṣe ni pé:

(i) Àwọn obìnrin Yorùbá ti máa ń kó ipa pàtàkì nínú òwò ṣíṣe
(ii) Bí a ṣe rí àwọn onísòwò alábọ́de bẹ́ẹ̀ la rí àwọn onísòwò aládàáńlá
(iii) Àwọn obìnrin Yorùbá ti ń ba àwọn òyìnbó dókòwò tipẹ́
(iv) Ipò tí àwọn onísòwò yìí dì mú nínú ètò ọrọ̀ ajé lo sọ wọ́n di ẹni tí ó ń di ipò ìṣèlú mú.
(v) Àwọn obìnrin máa ń ta ohun èlò ogun - èyí ló máa ń mu wọn di ọ̀rẹ́ àwọn olórí tó ń sètò ìjọba àti àwọn ológun
(vi) Àwọn obìnrin nípa ìsòwò àti ìjère a máa fi òwò wọn ran gbogbo àwùjọ lọ́wọ́.

Nínú fíìmù àgbéléwò ́Fúnmiláyọ̀ Ransome Kútì tí Túndé Babalọlá kọ, a rí òǹkọ̀fíìmù tí ó ṣàmúlò ìtàn ìgbésí ayé Olóyè Fúnmiláyọ̀ Ransome Kútì (MON) tí ó fi ìgbà kan jẹ́ olùkọ́, olóṣèlú àti ajàfẹ́tọ̀ọ́ ọmọnìyàn, pàápàá ajàfẹ́tọ̀ọ́ àwọn obìnrin. Ohun àkọ́kọ́ tí ó hàn nínú fíìmù yìí ni pé a rí àwọn obìnrin gẹ́gẹ́ bí onísòwò tí wọn ń mú ìmùgbòòrò bá ètò ọrọ̀ ajé àwùjọ Ẹ̀gbá, ìlú to jẹ́ ibùdó ìtàn fíìmù náà. Àmọ́ bí obìnrin tí ń mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ Ẹ̀gbá tó, ríré ní àwọn ọkùnrin tí ó jẹ́ aláṣẹ ìlú ń rẹ́ wọn jẹ nípa bíbu owó orí gọbọi fún wọn. Èyí ló bí ìjàgbàra tí Fúnmiláyọ̀ Ransome Kútì pète. Fúnmiláyọ̀ ló sì ṣaájú ogun náà. Èròǹgbà rẹ̀ sì ni pé kí ó tú àwọn obìnrin sílẹ̀ nínú ìgbèkùn àwọn ajóbìnrinṣòwò, ajóbìnrinjèrè, àmọ́ tí wọ́n kò fẹ́ kí àwọn obìnrin kó èrè ọjà délé.

Nínú fíìmù yìí, Fúnmiláyọ̀ tí ó jẹ́ olú ẹ̀dá ìtàn pinnu pé ó di dandan kí a gba obìnrin kúrò nínú ipò ẹ̀yìn tí àṣà, ẹ̀sìn, òfin àti àwùjọ lápapọ̀ tó wọ́n sí. Ìgbà tí Aláké àti àwọn Pàràkòyí ń da àwọn obìnrin láàmú nítorí owó orí, Fúnmiláyọ̀ ló díde láti kojú Dundee tí ó jẹ́ asojú àwọn òyìnbó amúnisìn tí ó wà ní ìjọba pé ìyá ọ̀hún to gẹ́ẹ́.

Fúnmiláyọ̀: Mr. Dundee, I am not here for my benefit, this is about the plight of the Ẹ̀gbá market women
Mr Dundee: I didn’t realize the Ẹ̀gbá market women had a plight
Fúnmiláyọ̀: Apparently, every time they say ámin’, the Ẹ̀gbá local authority taxes them
Fúnmiláyọ̀: Arákùnrin Dundee, n ò wá síhìn-ín nítorí àǹfààní ara mi, àwọn ìyálọ́jà tó wa ni Ẹ̀gbá lo gbé mi wá.
Arákùnrin Dundee: Èmi ò mọ̀ pé àwọn ìyálọ́jà Ẹ̀gbá wà ní ipò kankan o
Fúnmiláyọ̀: Ó hàn gbangban pé gbogbo ìgbà tí wọ́n bá ṣe àmín, àwọn aláṣẹ ìjọba ìbílẹ̀ ní gbá owó orí lọ́wọ́ wọn
Arákùnrin Dundee: Báwo ni tirẹ̀ tí jẹ to fi wá síhìn-ín?
Fúnmiláyọ̀: Mo wà síhìn-ín gẹ́gẹ́ bí obìnrin àti abiyamọ

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Fúnmiláyọ̀ kò di ipò ìṣèlú kankan mú, ó rí ara rẹ̀ bí adarí, ó sì di ipò olórí mú láàrin àwọn obìnrin náà títí tí ó fi fa àwọn obìnrin kúrò ní ipò ìmúnisìn tí àwọn aláṣẹ ìbílẹ̀ àti àwọn òyìnbó amúnisìn tí ń ṣe ìjọba fi wọn sí.

Ìfẹ̀hónúhàn lọ́kan-ò-jọ̀kan sì jẹ́ ọ̀nà tí Fúnmiláyọ̀ àti àwọn obìnrin ẹgbẹ́ rẹ̀ gbà láti gba òmìnira. Èyí fihàn pé obìnrin gbọdọ̀ fi ẹ̀mí ìsọ̀kan gba ara wọn sílẹ̀ láti jà fún ẹ̀tọ́ wọn ní gbogbo ọ̀nà.

Fúnmiláyọ̀: Women from all over Ẹ̀gbá land joined the growing protest...
Olóyè: There are more women assembled here than in all of the land of Ẹ̀gbá. Where did they come from?...
Pàràkòyí: My scout reported buses arriving this morning are full of women
Ọ̀tún: Fúnmiláyọ̀ Ransome Kútì! They heed her call
(Fúnmiláyò àwọn obìnrin láti gbogbo ilẹ̀ Ẹ̀gbá darapọ̀ mọ ìfẹ̀ónúhàn náà
Olóyè: Àwọn obìnrin tó kórajọ pọ̀ jú àwọn obìnrin to wà ní ilẹ̀ Ẹ̀gbá lọ. Ibo ni wọ́n ti wá?...
Pàràkòyí: Àwọn alamí mi sọ fún mi pe àwọn ọkọ̀ tó wọnú Ẹ̀gbá ni òwúrọ̀ kùn fọ́fọ́ fún Obìnrin
Ọ̀tún: Fúnmiláyọ̀ Ranmsome Kútì!
Wọ́n jẹ́ ìpè rẹ̀) (*Funmilayo Ransome Kuti*, 2024)

Àbùdá to hànde tí òǹkọ̀fíìmù yìí fẹ́ kí àwọn obìnrin ṣe àwòtà nínú ayé olú-ẹ̀dá ìtàn àti àwọn obìnrin tí ó jẹ́ olùrànlọ́wọ́ ẹ̀dá ìtàn ni níníìgbotà, jíjẹ́ akíkanjú, níní aápọn àti fífi àyà ran ìṣòro. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjọ́ ni àwọn obìnrin yìí fi ń jà tí wọ́n ń kọrin ọ̀tẹ̀.

Lílé: Okó lo fi ń sọkọ Ẹ̀gbá
Ègbè: A ó fòbò wa spọkọ rẹ
Ẹ̀yin okùnrin o
A**wọn obìnrin:** Òóò oò
Gbangba: A fẹ́ gba adé kúrò lórí Aláké
Àwọn Obìnrin: Báa wa (*Fúnmiláyọ̀ Ransome Kútì*, 2024)

Nínú orin òkè yìí, a ríi pé àwọn obìnrin pe ara wọn ní **ọkùnrin.** Èyí fi ìpinnu àwọn obìnrin náà hàn pé wọn ko kọ ikú. Wọn sì ti múra tán láti kọ ìrẹ́jẹ. Bákan náà, wọ́n ti ṣetán láti lo agbára abo èyí tó rọ̀ mọ́ ìṣẹ̀dá obìnrin láti rọ ọba lóyè. Wọ́n ti di akin tí kò gbọdọ̀ sojo. A tilẹ̀ le fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé akọnikùnrin-bìnrin ni wọ́n. Èyí tí yi ojú ti àwùjọ fi ń wo obìnrin bí ojo àti ohun èlò alàìlágbára padà pátápátá. Ẹ̀wẹ̀, bí a bá wo wúnrẹ̀n **okó** ati **òbò** bí ó ṣe hàn nínú orin yìí, ó fi agbára tí ó wà nínú ojú ará obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí Ọpẹ́fẹyitimi (2009) ṣe fi ìdí rẹ múlẹ̀. Lójú rẹ, ojú ara obìnrin ni ọkùnrin ń gba , ìkúnlẹ̀ abiyamọ kò sì ṣe fọwọ́ yẹpẹrẹ mú, ìdí nìyí ti èròngbà àwọn obìnrin náà ṣe ṣẹ mọ́ Aláké lára, nítorí pé àwọn obìnrin rẹ́yìn rẹ̀ nígbẹ̀yìn.

Guard: Kábíyèsí, Kábíyèsí
Osi: Sọ̀rọ̀!...
Guard: The women, they have breached our defences, Kabiyesi
Aláké: Ahhh!...
Guard: They are within the perimeter
Aláké: Olúfúnmiláyọ̀! O dẹni ẹ̀kọ̀ látòní lọ o
Ọ̀tún: Kábíyèsí ìdúró kò sí
Aláké: Ó yá, ó ya, ìjáfara léwu o
(*Orin ọ̀tẹ̀*)

Àríwísí ìṣesí àti ìhùwàsí Fúnmiláyọ̀ tí ó jẹ́ olú-ẹ̀dá ìtàn àti àwọn obìnrin Ẹ̀gbá tí wọ́n jọ ja ìjàgbara fi kún èrò pé onísòwò ni àwọn obìnrin látayebáyé. Bí wọn ti ń sowó ni wọn ń ko ipa pàtàkì nínú ìdàgbàsókè ajẹmọ́-ọrọ̀ ajé àwùjọ wọn. Owó orí tí àwọn aláṣẹ ń gba lọ́wọ́ wọn kún orísun ọrọ̀ ajé tí ó ń mù ètò ọrọ̀ ajé àwùjọ Ẹ̀gbá ìgbà náà rú gọ́gọ́. Ó tún hàn gbangba pe àwọn obìnrin ni ìgboyà. Ọ̀pọ̀ eṣú wọ́n sì le yagi. Àti pàápàá, ajàfẹ́tọ̀ọ́ ọmọnìyàn ni àwọn obìnrin kan gẹ́gẹ́ bó ṣe hàn nínú *Fúnmilayọ̀ Ransome Kútì*.

Àgbálọgbágbọ̀

Bí a bá wo àwùjọ YOrùbá lóde òní, a óò rí i pé ipò àti ipa obìnrin nínú òwò ṣiṣe kò kéré rárá. Láwùjọ Yorùbá, àìmọye obìnrin ló jẹ́ oníṣòwò yálà alábọ́dé tàbí aládàáńlá. Àrígbámú tí a rí nínú iṣẹ́ yìí ni pé bí obìnrin bá rí ààyè wọn le dípo adárí mú fún ìdàgbàsókè àwùjọ lápapọ̀. Ó sì hàn gbangba nínú àfihàn àwọn obìnrin inú àṣàyàn iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ tí a yẹ̀ wò pé ìpín pérété ni ìpín àwọn obìnrin nínú ipò ìṣèlú, bẹ́ẹ̀ igi lẹ́yìn ọgbà ni wọ́n jẹ́ fún ọkùnrin gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú *Olú Ọmọ* àti *Ẹfúnróyè Tinúubú*. Bákan náà, ó tún hànde gbangba pé àwọn obìnrin kan kọ ìrẹ́jẹ, wọ́n sì ṣetán láti fi ohùn wọn lọ́lẹ̀ nígbà tí ó bá yẹ. Ìdí nìyí tí fíìmù *Fúnmilayọ̀ Ransome Kuti* fi fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ríró obìnrin ní agbára nípa ìmọ̀ ẹ̀kọ́ àti ọrọ̀ ajé yóò ràn wọ́n lọ́wọ́ láti ja àjàgbara kúrò nínú ìrẹ́jẹ akọ àti onírúurú ìmúnisìn. Ní àkótán, iṣẹ́ yìí fi hàn pé onírúurú ọ̀nà ni obìnrin fi í hjẹ́ obìnrin láti mú ìtẹ̀dsìwájú àti ìdàgbàsoke bá àwùjọ wọn, pàápàá àwọn obìnrin akẹgbẹ́ wọn. Ìdí nìyí tí iṣẹ́ fi dá ani àbá pé kí àwọn ìjọba tún èrò wọn pa nípa fífi ààyè gba obìnrin nínú ipò ìṣèlú àti ohun gbogbo tó rọ̀ mọ́ ìlọsíwájú àwùjọ àti ohun gbogbo tó rọ̀ mọ.

Ìwé ìtọ́kasí

Abimbola, W. (1968). Ìjìnlẹ̀ Ohun ẹnu Ifá – Apá kìíní. London: Collins.

Adejumo, A. (2017) Ïpo Wo Lobìnrin wà Nínú Ìtàn Àròsọ Fágúnwà"in Adélékè Adéẹ̀kọ́ and Akin Adésọ̀kàn (eds). Celebrating Literary History: Ibadan: Bookcrafts.

Adejumo, A. (2022). Negotiating Cultural Dynamism: Woman and Gender Relation in the Novels of D.O. Fagunwa in Àkàngbé C.A, Orímóògùnjẹ́ O.C. & Falẹyẹ A.A. (Eds). *New Trends in Yorùbá Language, Literature and Culture*. Ibadan: Clemeve Media Konsult, Pp 144-166.

Adeleke, A. (2017) "Sex, Gender and Plot in Fagunwa's Adventures" in Adeleke Adeeko and Akin Adesokan (eds). Celebrating D.O. Fagunwa Aspects of African and World Literary History. Ibadan: Bookcraft, 2017.

Awe, B. (1992). " Iyalode Ẹfunṣetan Aníwura (Owner of Gold)", in Bolanle Awe (ed). Lagos: Sankora Publishers.

Babalola, S. A. (2001). Àwọn Oríkì Mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n. Lagos: Longman Nigeria Plc.

Babalola, T. (2024). *Funmilayo Ransome Kuti*. Produced by BAP Productions, Lagos.

Bolarinwa, A. (2019). "Women in Adébáyọ̀ Fálétí's Poetry". *Yorùbá Studies Review*. Ibadan: Library Press OUF. Pp 135-150.

Denzer, L. (1994). *Yorùbá Women*: A Historiographical study. International Journal of African Historical Studies, vol. 27, pp 1-39.

Fadipe, N.A. (1970). *The Sociology of the Yorùbá*. Ibadan: University Press.

Hudson-Weems, C. (1994). *Africana Womanism: Reclaiming Ourselves.* Troy: Bedford Publishers.

Kolawole, M. (1997). *Womanism and Africa Consciousness*. Africa World Press. New Jersey.

Isola, A. (1983). *Olú Ọmọ*. Onibonoje Press and Book Industries (Nig.) Ltd.

Isola, A. (2009). *Ẹfunroye Tinuubu*. Ibadan: DB Martoy Books

Isola, A. (1970). *Efunsetan Aniwura*. Ibadan: University Press Plc.

Johnson, S. (1921). *The History of the Yorùbás*. Lagos: CSS Bookshops.

Nwajiaku, I. (2004). "Representations of Womanist Discourse in the Short Fiction of Akachi. Ezeigbo and Chinwe Okechuckwu. In *New Women's Writing in African Literature*, volume 24, (Eds) E. Emenyonu. New Jersey: Africa World Press.

Ọmọtayọ, A.A. (2025). Representations of Sexual Orientation in Twenty-first Century African Prose Narratives. A Thesis in the Department of English, University of Ibadan.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, A. (2009). “Women of the World” in Yorùbá Culture. Women in Yorùbá Culture: A Dozen of Academic Articles Ibadan: Penthouse Publications., pp.121-133

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

Para citar este texto (ABNT): ADÉJÙMỌ̀, Àrìnpé Gbekelolu. Ìṣàfihàn onírúurú ọ̀nà ìjóbìnrin nínú àṣàyàn iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ yorùbá. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 127-139, jan./jun.2025.

Para citar este texto (APA): Adéjùmọ̀, Àrìnpé Gbekelolu (jan./jun.2025). Ìṣàfihàn onírúurú ọ̀nà ìjóbìnrin nínú àṣàyàn iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 127-139.